# EKO AKETE.

## IWE IROHIN OSOSE.

VOL: I. No. 7. SATURDAY, AUGUST 26, 1922. THREEPENCE.

*Editor*:—ADEOYE DENIGA,
*Office*: 24, Williams Street,
P.O. Box 286
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

CHIEF SECRETARY'S OFFICE 28 AUG. 1922 LAGOS

### GBOHUN-GBOHUN.

### ARA ỌRUN KẸ Ẹ, KẸ Ẹ!

A gbọ pe ni ijọ kẹsan oṣu yi, awọn egungun ti nwọn to ọrinlenigba (280) ṣe etutu ni Ita Ake, Abẹokuta fun rirọ ojo: iya-afin kan "Aniwura" ti o wa ni Abẹokuta nigbana, sọ fun ni pe egungun abami kan wa lara awọn egungun na ti o nje Ribiribi, ti o fi nkan bi titobi-ile ṣe ori!!!

### OṢE, ỌKUNRIN LỌ!!!

A ba Oloye Ọbanikoro Onifilafunfun kẹdun ọfọ ti o ṣẹ ẹ ni lọlọyi, nipasẹ iyekan rẹ ti a npe ni Ajayi to ṣalaiṣi ni Oṣogbo: k' Ọlọrun dẹ 'lẹ fun u.

### A FI ORIN JIṢẸ OLUWA.

Inu wa dun lati ri ọrọ wa Ọgbẹni E. J. Ọjẹlabi nibi, to de laipẹ, ti o si tun bẹrẹ wasi rẹ ni igbọro: o mu ọmọde-kunrin kan ti o to ọmọ ọdun mẹfa wa, ti o si nka pupọ ninu ọrọ *Bible* jade lati ori; ọmọ na "ṣe bi arira" nigbati Ọgbẹni na ṣe isin Wasi kan ni alẹ *Monday* ijọ 14 oṣu yi, ni ita *Garber* ti Ọgbẹni Akin Adeṣigbin ṣe Alakoso rẹ.

## ẸGBA ỌMỌ LIṢABI.

Awọn Aṣaju diẹ ninu awọn Ẹgbẹ Owu ti ilẹ yi lọ ki Ọba Owu ni Abeokuta ninu ọsẹ diẹ tokọja: nwọn si ya bara lati kansẹ fun Alake ni Afin ki nwọn to pada bọ sile. Ninu awọn to lọ ni iiwọnyi, Ọgbẹni Akin Adeṣigbin, Ọgbẹni A. Gbogboade, ati Ọgbẹni Kẹhinde Oduwọle.

## ỌGA NI PENNINGTON, ẸBỌRA NILE ẸJỌ.

Ile ẹjọ awọn *Jury* (*Criminal Assizes*) pari ni *Tuesday* ijọ 15 oṣu yi: kosi ẹnikẹni to lọ woran tabi to ni Ẹjọ ni ile Ẹjọ yi lati igba ti nwọn ti bẹrẹ rẹ ninu oṣu yi, o nlọ si ọsẹ meji nisisiyi, ti koni kan saara si Adele Adajọ Agba *A. R. Pennington* Ọlọla, fun suru, ayan, lakaye, ati iwadi-nkan finnifinni to fi da gbogbo Ẹjọ ti Agbẹjọ-ro-ọba muwa siwaju rẹ ni oṣu *Assize* yi. Ara-lile, Ẹmigigun, ọgbọn kun ọgbọn lati ọrun wa, ni a tọrọ fun nyin, Adajọ Abẹrinṣefuja.

## IKU OLORI AYABA.

A ba awọn ẹbi idile Ọba ti ita *Vincent* ati ni isalẹ Ekọ kẹdun iku olori aya Dosunmu Ọba, ti o ṣẹlẹ ni ijọ 13 oṣu yi; a gbe oku na lọ sin ni oko baba ni ijọ keji, pẹlu ọkọ ajẹ ati ariwo nla.

## IYAWODUN LỌṢINGIN.

A gbọ pe Ọgbẹni C. Ibarẹ Akinsan, Akọwe Agba ti Iṣẹ Ọba nihin, gbe iya-afin Martha Fọlaṣade, Alarede Ọgbẹni A. W. Shitta lailai, ni iyawo ni *Church* Olowogbowo ni ijọ *Monday* ọsẹ yi.

## EKO AKETE.

EKO SATURDAY, AUGUST, 26, 1922.

### A BA FI EYI ṢE 'WỌ, IWỌ JẸ FẸ?

Anu ṣe ni pupọ lati ri pe Dr. O. ỌBASA Ọlọla, ara Ikija mu ọrọ awọn Imale lọsi Ajọ Igbimọ Ọba ni ijọ 19, oṣu *July* tokọja, gẹgẹ bi a ti ri ka ninu Iwe-irohin ọsọsẹ ti Ijọba (*Nigeria Gazette,*) ti ijọ 17 oṣu ti a wa yi. Nigbati a ka gbogbo aroye ti Onişegun Ọlọla yi sọ, o fihan gbangba pe apakan lo pọ si ninu ọran na, o si nfẹ sọpe ki Ijọba wa wọrọkọ fi ṣ'ada lati da si ọrọ na gẹgẹbi ẹnipe ọro ilu ni: ohun to si dun ni ju nipe Ọlọla Onişegun yi ko kọminu lati la orukọ ADAM A. IMAṢAWUN mọlẹ wa, pe on ni ọlọtẹ (*ring-leader*) ninu awọn Janma Musulumi ti o ni ki awọn ọlọpa mu awọn ti a kolọ si Ọgba wọn nigbati ija kan bẹ silẹ larin awọn Imale to wa ni Mọṣalaşi Nla ti ita *Victoria*, ni ọjọ ti ko pẹ yi. Ka fi enia sun ẹsun Ọlọtẹ niwaju Ijọba ki nşe ohun kekere: irufẹ ẹni bayi nilu yẹ ki o mọ pe ninu ọrọ-tian-tian yi, orukọ ṣoro da: nje bi ẹniti a darukọ rẹ yi ba fi ofin mu Onişegun Ọlọla yi nipa pe ki o wa sọ asọye tan "*Kolu*" bi on ti şe di Ọlọtẹ ninu ọran yi nkọ, kini Onişegun yi yio ri sọ? Ko si ọmọ-ileiwe kan ti ko mọ pe bi otiwu ka wipe ija nbẹ ni igboro to, awọn Ọlọpa ni ẹniti Ijọba ti yan lati ma bojuto pipana iru ija bẹ, o si ti ni loju pe Onişegun Ọlọla yi fi ara rẹ sipo ẹniti o gbagbe nkan wọnyi titi Sẹkitẹri Ijọba, *Lieutenant-Colonel* F. JENKINS, C.M.G. Ọlọla Alakoso Ajọ Igbimọ na, fi tẹ otitọ yi mọ ọ leti.

A korope irufẹ işẹ ati ma jin-ara-ẹni-lẹsẹ-ẹhin bayi ni Ijọba ni ireti pe ki Onişegun Ọlọla yi wa şe fun ilu, nigbati Ijọba yan ninu oşu *August* 1921, sinu Ajọ Igbimọ Ọba Ọlọla yi lati wa şe Oju-Ilu.

Gẹgẹbi Sẹkitẹri Ọlọla ti sọ, ọmọ ana mọ pe ọrọ-Isin ni ede-ai-yede towa larin awọn Imale ni igboro ilẹ yi, eyi kosi kan Ijọba ni didasi, ayaşebi irufẹ gbọmisi-omikoto bẹ ba mu ruke-rudọ wa, ati ifoya ẹmi, nilu.

A dupẹ lọwọ Ijọba wa to tubọ fi eyi han gedegbe ni ijọ Ipade yi gẹgẹbi ati ri ka ninu Iwe-irohin na: a si tanma pe irufẹ iwa Lilẹdi Ọmọ-ẹnikeji ẹni bayi-papa lọdọ Ijọba ninu ipade irufẹ-eyi ti o lodi si iwa ẹniti o npe ara rẹ ni ọmọ ẹhin Kristi, ki yio jẹ ohun ti Onişegun Ọlọla yi, yio tun ma fi şe ohun ayọ lati hu si ẹnikẹni mọ nijọmiran ibaşe Imale, Onigbagbọ, tabi Abọrişa, "Agbalagba ki nşe langba-langba."

---

## IPO AWỌN ỌMỌDE.

Eko
26th August, 1922.

Letter No. 5.

Ẹnyin Ọrẹ Mi Kekere,

Inu mi dun pupọ lati kọ iwe yi si nyin, mo si ro pe yio ba nyin ni alafia ati ara lile gẹgẹ bi mo ti wa nihin. Ẹ ku işẹ nyin. Alafia kọ ni awọn Obi nyin wa bi? Mo nşeyemeji lọkan mi pe gbogbo nyin kọ ni o nka iwe-irohin, bi o ba jẹ otitọ ni eyi,

kini ẹni duro de, akoko daradara ni eyi jẹ fun nyin, awọn aṣiwaju nyin ko ri irufẹ iwe bayi, ṣugbọn bi o ba ṣe pe ẹ ko mọ pe a nkọ irufẹ iwe bayi si nyin, ẹbi awọn obi nyin ni, ẹbi awọn olukọ nyin si ni pẹlu. Ṣugbọn a ni ireti pe eyi yio ṣe nyin ni anfani bi ọjọ ba gori ọjọ, bi oṣu ba gori oṣu, bi ọdun ba gori ọdun.

Ọrọ ti a o fi gba ara wa ni iyanju lọsẹ yi ni IFORITI OHUNKOHUN TI E BA NSE, eyiti awọn awọn Oyinbo npe ni *Perseverance*. Ninu ohun gbogbo ti ẹ ba nṣe, ẹ ma kọ lati ma foriti i titi de opin. Ọpọlọpọ ọmọ li o wa larin nyin ti ko le foriti ohun ti nwọn ba ni ko ṣe, ti o jẹ pe bi o ba ti ba wahala tabi iṣoro kekere kan pade, a sa lọ bam-bam, a si ma kun bi Oloyin-ata. Ọpọlọpọ ninu nyin ni Olukọ ma kọ ni iṣiro kan tabi itumọ titun kan ti ko ni ye wọn wo bi o ba de ile tan. Bi ẹni bẹ ba wa larin nyin, ki o bẹrẹ lati oni lọ lati ma kọ bi a ti ṣe nforiti nkan. Bi awọn obi nyin ba bẹ nyin lati ṣe nkankan fun wọn, bi o ba ni nyin lara lakọkọ, mo bẹ nyin ẹ ma sa fun nkan na, ẹ sa ma foriti i. Bi Olukọ nyin ni ba kọ nyin ni ẹkọ titu kan, ti ko ba ye nyin, ẹ foriti i bi o ba pẹ titi ẹ o mọ ọ. Awọn Oyinbo ni o ma npa owe kan nwọn ni "*Perseverance surmounts difficulties*." Eyi ni pe," Iforiti ima ṣẹgun iṣoro gbogbo."

Bi o ba fi kọra lati oni lọ yio ṣe nyin ni ire ti a ko le fi ẹnu sọ. O si ma nmu ere wa fun awọn enia ti o jẹ pe nwọn ni ẹmi iforiti ninu ohun gbogbo ti nwọn ba nṣe. Eyi mu mi ranti itan otitọ kan, eyiti mo fẹ sọ nisisiyi. Ni ọjọ kan, Ọdọmọkunrin kan wa ni ilu kan ti orukọ rẹ njẹ Maṣemẹlẹ, o lọ si ilu kan lati ṣiṣẹ nibẹ, orukọ ilu ti o lọ ṣiṣẹ yi njẹ Ọlẹkoraiyewa. O de ibẹ ko ju ọsẹ mẹrin lọ ni Ọga wọn ti orukọ, rẹ njẹ Aṣetiun-ara-rẹ pe gbogbo awọn Akọiwe rẹ pe on fẹ iwe pataki kan (*Document*) ni Office, a ti pe inu on yio dun pupọ bi ẹnikẹni ninu wọn ba le ri iwe na fun on; gbogbo awọn Akọwe ti o nṣiṣẹ labẹ Ọga yi jẹ mejila, gbogbo wọn wa iwe yi nwọn ko ri i, nigbati o di ọsẹ keji ti nwọn ti nwa a arẹ mu gbogbo wọn afi Maṣemẹlẹ nikan ni arẹ ko mu; o nforiti i titi, bi o ti nwa a lọwọ awọn ẹlẹgbẹ rẹ nfi rẹrin, nwọn fi ndapara, ayaṣe pe bi nwọn ti fi nrẹrin Ọga wọn nṣọ wọn, o si dakẹ ṣe o mọ ohun ti o ma ṣe ninu ara rẹ, bi nwọn ti rẹrin yi, Maṣemẹlẹ ko sọ ireti nu, o nwa iwe na lọ ṣa ni, nigbati o di oṣu kan gbako ti Maṣemẹlẹ ti nwa iwe yi o rini ibiti gbogbo wọn ko ni ireti pe o wa. Nigbati Maṣemẹlẹ ri iwe yi Kẹkẹ pa mọ wọn lẹnu, nwọn ko le ro to. Maṣemẹlẹ mu iwe yi tọ Ọga wọn lọ, o si jẹ iwe ti nwọn nwa gan. Inu Ọga wọn dun pupọ. Orukọ ṣa ma nro na; lojiji ati lai sọ fun ẹnikẹni, Ọga wọn ẹniti orukọ rẹ njẹ Aṣetinu-ara rẹ pe Maṣemẹlẹ o ni ki o bọ si "Office" ti on papa, eyiti nwọn npe ni "Agent.s Office" ni ede Oyinbo. O si fi owo kun owo Maṣemẹlẹ ni i lọpo meji. Ẹnu ya awọn ẹlẹgbẹ rẹ pupọ, bayi ni Maṣemẹlẹ di Ọga gbogbo awọn ẹgbẹ rẹ, bi ẹnikẹni ninu wọn ba fẹ ri Ọga wọn, o ni lati ri Maṣemẹlẹ na. Ẹ ko ri nkan, o dara ki enia ma foriti nkan gbogbo ti enia ba nṣe. Ẹnyin ọrẹ mi, mo bẹ nyin ki ẹ kọ ọgbọn lati inu itan kekere yi.

"*If at first you don't succeed, Try, try, try again.*"

Emi ọrẹ nyin nitotọ,
"ELETI-ỌFẸ"

---

## A BRIEF REPORT.

### Meeting held to explain the object of starting "EKO-AKETE," by OTITỌ-KORO.

A public meeting in which was explained the Object as well as the necessity of starting "Eko-Akete" was arranged by Mr. Adeoye Deniga (The Editor) and took place at Ilupesi Hall Great Bridge Street, on the 22nd June, 1922.

Mr. Herbert Macaulay, C.E., who was to have occupied the Chair that afternoon being absent, due it is said to slight indisposition, Iman Amọdẹ was called upon to occupy the Chair. Mr. Deniga, opened the meeting at about 5. p.m. with a long explanatory as well as instructive address on the Yoruba Literature and the necessity for a Yoruba Newspaper in the local world of journalism. In the course of the address which lasted over 40 minutes, copies of every periodical published in Lagos, were held out, one after another, for exhibition among the audience.

General consultation, whispering etc. among the hearers followed the conclusion of the opening address.

The Chairman rose and gave a short speech in form of a reply to the address. He said among other things:—"What Mr. Deniga brought this afternoon is a very good scheme. Since you (*i.e.* Mr. Deniga) have been forming the idea, God too has been helping you. It is indeed a thing by which the whole town would be benefited. May God help you in this venture. We followed all the points raised in your address and are glad, having children in School ourselves. All those "bigmen" of the town whom you invited must have unavoidably been absent. But be assured I shall deliver message to them. You will be good enough to go on in your

good work until through the help of God you will be able to summon a larger meeting when the Country will be able to appreciate your work" This was followed by Mr G. F. Oroye who said *inter alia* :—"We thank the people present here this afternoon for their attendance. I have been following the speeches very closely. There are many reasons why a Yoruba newspaper is necessary particularly here in Lagos.

Many things have been going on in town with which a large section of Yoruba speaking or reading people are not acquainted. You may remember many years ago when attempt was made to gag the Press in Lagos. Petitions were sent by great men of the town, by Churches, Societies etc.

At last the Prayers of the people were granted and the existence of the Press continued. The press is a very valuable medium.

What Mr. Deniga said is all right but as a child he ought to receive your support. As you said he ought to call a bigger meeting, but that does not mean that we here this afternoon cannot think for ourselves" The meeting was closed (at about 6.30 p.m.) with a short speech by Mr. Deniga in which he said among other things :—

"I thank you all very much for your attendance I am greatly encouraged by the speeches of the Chairman. But lest you run away with a wrong idea, I must assure you that I have been managing Newspapers not to-day so there need not be any fear about political questions. Again, I am very thankful to you all." The meeting which was conducted in Yoruba throughout contained about 60 hearers and some notable people were present. Thus ended a meeting to tell the Lagos Public of the necessity to start a Yoruba Newspaper in these days. Although I have unavoidably left much to be desired (and for this I ask the excuse of my readers) yet the few words I have been able to get down speak for themselves.

"Enough" says an author "is as good as feast." Mr. Adeoye Deniga has done enough in furthering the improvement of our own literature, and in all his undertakings he should be wished every success.

Lagos, August 1 1922.

## ELETI-ỌFẸ AND THE MOHAMMEDANS.

To the Editor "Eko Akete."

Sir,

I read with much disgust an unjust attack made on the Mohammedans of Lagos by one Eleti Ọfẹ in your issue for August 5.

I am sorry for not being a good hand in Yoruba writing but believe this short letter (in English) will help to refute his misleading no less nonsensical statements.

It is Shakespare who wrote :—

"This above all,—to thine own self
be true,
And must follow as the night
the days,
Thou canst not then be false to
any man."

I am by no means purporting to show that the Mohammedans have no blame in the crisis. On the other hand, I am trying to tell Eleti ọfẹ. and thereby any one who shares his opinion, that Mohammedans are not the only Section responsible. Now the question necessarily arises whether Eleti-ọfẹ is true to himself or whether he is not Eleti-kunkun, the opposite of what he calls himself.

"Mohammedans" says he "are hard-hearted. They brought their troubles to Eleko three years ago etc."

This is a simple passage from the Yoruba Epistle of Eleti Ọfẹ and it is enough to show his disposition.

Can any one, same and level headed blame the Mohammedans alone for the present confusion in the political life of the Country ; Look back to the early stages of Eleko crisis. Tell me how many Mohammedans and how many Christians are in the *famous* "13" How many do you find in the *Star Chamber ?* Is it a Mohammedan who made such a bad press propaganda misrepresenting the matters every now and again and adding new fuel to the already burning political fire ? Is it a Mohammedan who said that Eleko is a *dead tree* and should not be denied a decent burial ? Go to the root of the Mohammedan crisis and what do you find ? Christians of course ! The Mohammedans. left to themselves, their affairs would not have come to a crisis.

At least, it is a gross injustice on the part of Eleti Ọfẹ to saddle the bulk of the Mohammedans (who are mostly illiterate and unenlightened) with the whole blame.

To settle the present crisis lies very much in the hands of you Christians—you have the papers in your hands ; you have the ink, the pen ; nay, you know the shortest and best roads leading to the Government House. So you stand a better chance in the whole confusion.

Again, I ask, is Eleti Ọfẹ true to himself ?

Your etc.,
OTITỌ-KORO.

## IROHIN IKỌ TI ẸGBẸ OWU EKO RAN SI ỌBA OLOWU NI ABẸOKUTA.

Lati igbati a ti fi Ọba Olowu ti Owu Abẹokuta, jẹ Baba Ẹgbẹ Owu ti Eko ni a, ti ro pe o tọ o si yẹ jọjọ pe ki a yan awọn diẹ ninu Ẹgbẹ ti yio lọ ki Baba Ẹgbẹ wa ni Abẹokuta. Nitoripe Ẹgbẹ ati Baba Ẹgbẹ ngburo ara wọn ninu iwe kikọ tabi nigbamiran lati ẹnu awọn iranṣẹ. Lai fagun lọ titi, ninu ipade ti a ṣe ni ọjọ kẹfa oṣu July, 1922, ni a yan awọn Ọgbẹni Akin Adeṣigbin, Alabojnto Ẹgbẹ, George A. Cole, Akapo Owo, J. K. Oduwọle, Adebẹṣin Adekanbi, E S. Akiyẹmi ati Adelani Gbogbo Ade, Akọwe Ẹgbẹ, pe ki nwọn lọ ki Ọba Olowu ni Abẹokuta, ki nwọn si ki awọn Ọba mẹtẹta yoku pẹlu.

Awọn ti a yan wọnyi gbera ni ọjọ *Saturday* ti iṣe ọjọ karun oṣu yi, nwọn si wọ ọkọ ilẹ ni agogo mẹta ọsan, nwọn de Abẹokuta ni agogo mẹjọ alẹ. Gbogbo awọn mẹfẹfa wọ si ile Soke ni Agọ-Owu ninu ile Akọwe Ẹgbẹ wọn. Ni iyalẹta ijọ keji, ti iṣe ijọ Sunday, ijọ kẹfa oṣu yi, ni oniṣẹ wa kan Ọba Olowu pe a wọlu lalẹ ana, a si fi ohun ẹbun ti Ẹgbẹ fi ranṣẹ si Ọba ṣọwọ si loro na. Inu Ọba dun pupọ nigbati o gbọ pe a de, o si fesi lẹsẹkanna pe ki a ki wa ku abọ, ki a si m bọwa si afin Owu ni agogo mẹrin ọjọrọ. Nitoripe ko ni si aye fun to lati gbadun wa larọ ọjọ ọsẹ, Ọba fẹ lọ jọsin ni Ile Ọlọrun awa na si fẹ ṣebẹ.

A mura a si lọ sin ni Ile Ọlọrun ti Ake, nibiti a gbe pade ojulumọ pupọ, nigbati a pari isin tan kato jade a sunmọ Ọba Alake a si ki. Lẹhin na a tun gbera pa lati Ake lọ si Ọgbẹ, a si tun ba awọn Ijọ Ile Ọlọrun Ọgbẹ sin di agogo mejila ọsan, nibiti Ẹniọwọ Kufeji gbe njiṣẹ Ọlọrun nisisiyi. Lẹhin igbati apari isin, ti a si ki Ọgbẹni Kufeji pẹlu gbogbo ojulumọ tan, a dari wale. Nigbati a jẹ onjẹ ọsan tan, onikaluku wa bẹrẹ si mura lati lọ foju kan Ọba Olowu. Ẹniti a nwo ki isa woran, igbo ni imura awọn ẹlẹgbẹ mi yoku, nwọn ṣe ọṣọ niba jaba, nwọn si fihan pe Eko ni nwọn ti wa.

Ni agogo mẹta on abọ la... Owu, a si de Afin Olowu ni a... wọle, a ba ọpọlọpọ enia lọtun ati ... ba awọn Ijoye Owu nipo wọn, nw... gẹgẹ bi ipo oni kaluku wọn tiri, ... lọtun awọn yoku lesi Ọba wa, awọ... Ogun ati awọn Ologboni lẹgbẹ kini... Ọba papa gunwa larin lori itẹ ... foju kan Ọba lokere la da op... silẹ titi a fi sunmọ Ọba. Ọba... lori itẹ rẹ, o pọn o ri fo, awọ a... pere, o dun wo gẹgẹ bi o ti rọgb... wẹku, mọna ni ade ori rẹ ndan, ... onikalakini ko ṣe fẹnu juwe, a f... ẹni ri. Bata ẹsẹ rẹ pẹlu kokan... rẹ.

Lẹhin igbati a fori balẹ fun... gbogbo wa nikọkan gẹgẹ bi a ... onikaluku fun, o bere ile, o si ... si ki gbogbo awọn Ijoye tọwọ... lẹhin eyi Ọba paṣẹ pe ki ... gbọngan ti ima gba alejo... de wa, a si ti tẹ itẹ fun ... awọn Ijoye wọle tele wa, oni... si ipo rẹ gẹgẹ bi aṣa wọn. Lẹ... bọṣọ igunwa rẹ silẹ tan, alore s... o nbọ, o si gbọna ẹburu t... si wa, gbogbo wa si da ... Aṣọ ati Ade ti Ọba gbe ... yatọ lọpọlọpọ si takọkọ ... ko ṣe fẹnu sọ, o dara lọpọlọpọ.

Lẹhin igbati Ọba joko tan, Ak... dide, gẹgẹ bi a ti ran, o si jẹ g... Ẹgbẹ fun Ọba ati awọn Ijoye... dun pupọ, o si fi gbogbo ọrọ wa... Ijoye lọwọ pe ki nwọn sọsi. Nw... nikọkan gẹgẹ bi ipo wọn, nwọn si s... wa, nigbati a gbọ tẹnu awọn Ijoye t... papa wa fi orisirisi akọ ọrọ pa... aroye wa. Nigbati a sọrọ ti E... tan, Ọba paṣẹ pe ki a lọ si ile on... fẹnu pa nkan jijẹ ati mimu diẹ, ... gbo wa gbẹradi a si ṣe gẹgẹ b... Ki la o ri, a ba table onjẹ ta ti f... bo lori, a si ti ko awo ati ife loris... lilo wa.

Ko si ṣiṣe ko sai ṣe, a sun kẹrẹ ... onjẹ, Ọba joko nigberi *table*, Ọgb... Adeṣigbin jọko kọju si Ọba, aw...

...ẹlu Arẹmọ Ọba joko nibu ọtun ...diidina, gbogbo wa jẹ enia mẹjọ. ...ila ni fun ẹnito ba ri Ọba ba jẹun, ...adun onjẹ na tobẹ ti a ko fi mọ igbati ...ẹrankun. Lẹhin ta jẹun ta si mu ...ẹyan Ọgbẹni Akin Adeṣigbin pe ko ...ilera Ọba wa, nigbati o si pari ọrọ a fi tọkan tọkan mu nkan si. ...a papa da lohun. A si wa pe ...pe ko sọrọ leri ilera gbogbo a ni Ilẹ *Nigeria* ati nibomiran ...igbati o dani duro, gbogbo tun ...an mu nkan si. Lẹhin eyi a ...ọla fun Ọba wa, a si kuro ni Table.

...*onday* eyiti se ọjọ keje oṣu yi, Ọba, a gba aworan loriṣiriṣi ọna ...kan Ọba ninu aṣọ igunwa rẹ, ...ori ẹṣin, ẹkẹta Ọba pẹlu awa ...meeting Eko ati ẹkẹrin Ọba pẹlu ...a shorthwo wa ti tẹ awọn aworan ...said ...rẹ ri wọn le fẹsẹ kan de ọdọ ...ijọ kanna, lagogo marun fẹrẹ ...ba tase akoko ta fun wa, a gbera ...ike onina ti Ọgbẹni Lambo Ajayoyo di Afin Ake, ka to de ibẹ, ...not...*mbe* Aṣoju Ọba Alake, ...pọ ọna de wa, o si mu wa ...Ọba Alake de, gẹgẹ bi aṣa ilẹ ...poro kabiyesi bo, o fẹrẹ ma ti fidi Akọwe Ẹgbẹ daro Ẹgbẹ ti on pẹlu wa ri fun, Alake ja lẹsẹkanna, o si ...a nwọn si gbara wọn lọwọ awo. ...ni a wa tọka onikaluku wa iun ẹnito bawa sọrọ fun biwọn iṣẹju ...n lori iro buburu ta ngbọ ta si nri iwe irohin, Alake sọ fun wa pe ka ...wọn, ati pe irọ funfun ni nwọn npa, ...ye, wa ninu isẹ rere to ti ṣe, to si un itura gbogbo Ẹgba ati Owu. Alake ba wa sọrọ tan o fi wa le ...*itcbmbe* Aṣoju rẹ lọwọ pe ko jo. Were bi ọmọde meji nsere ...kan mimu dalẹ ti onikaluku wa ...o banu rẹ jọ.

...eyi a gbera pa o di Afin Oṣilẹ, Ọba botijẹpe ko mọ wa ri, ṣugbọn a jẹ bawa tọwọ tẹsẹ, o si bawa sọrọ pupọ ...iṣiri. O gbe nkan mimu siwaju wa, o si tun fi ṣile mẹwa abọ ṣewa lalejo Okan ninu awọn ako inu ọrọ Ọba yi nipe, ki a madẹkun ma ṣi gbogbo awọn Ọba leti dara dara, ki wọn ba le ma ṣe ifẹ Ọlọrun ati ti awọn enia ti wọn jọba le lori. Yo si jẹ ohun ti o dara lati gbọ pe Ọba yi ko mọ ọti oyinbo mu.

Ọgbẹni Akinwande Thomas pe wa si ibi ase nile rẹ, nijọ Tuesday, ijọ kẹjọ oṣu yi, a ba jẹ a si ba mu, o si tun fun wa ni kẹkẹ onina rẹ fun lilo wa, eyiti a gun yiluka titi a fi de Afin Ọba Agura, a kede fun Ọba yi pe a de, nigbati o si yọ siwa, o bere ile ati ọna wa, o si daro pe on ko mọ pe a o ba on lalejo, nitorina o ṣeleri pe on yio ma fi nkan alejo wa ṣọwọ siwa. A wa fabọ si Afin Olowu, a dagbere fun Ọba wa pe ki Ọlọrun ma foni ni yawa, ki Ọba kopẹ lori oye, kawa na si dele lalāfia.

Ọba Olowu fun wa ni pọnwun meji ati ẹran kan, lai ka ase ti ọjọ *Sunday* ati ti onjẹ rẹpẹtẹ to se to si gbe ranṣẹ siwa nijọ *Monday*. Ijafara ko tun si mọ, a ko sinu kẹkẹ onina wa, a si wa tarata lọ si Lafẹnwa nibiti a gbe wọkọ *Railway* to gbe wa de Eko ni agogo marun kọja.

Ọpọlọpọ nkan lo nfẹ akiyesi dara dara ninu gbogbo afin awọn Ọba wa, kosi eyi ti koyẹ ka tunkọ ninu wọn, afi ti Ake ti Ologbe Gbadebọ kọ nigbá aiye rẹ. Aini akọwe ti Oye ye, ti yio si ma ṣoju wọn ninu ohun gbogbo gẹgẹ bi ti Alake bu wọn ku: bi Ijọba Abẹokuta ko le ṣe inawo eyi, o yẹ, o si tọ fun, Ọba yoku ko gba irufẹ akọwe bayi lapo ara wọn. Ẹnu ko le ya nipe a kọ iwe kan si Ọba Olowu, eyiti a *Register* ni Eko nibi leṣin, o to wọn oṣu mẹrin lẹhin na ti ọga awọn apinwe kiko ti Eko fi iwe na ṣọwọ siwa pe, nwọn da iwe wa pada, nitoripe nwọn ko rẹni gba lọwọ wọn ni Abẹokuta; bo ṣepe Olowu ni Akọwe tirẹ ni, yio mọ bi ati gba apoti ni ile iwe kikọ (*Postal Box*) ninu eyiti a o ma ko iwe Olowu si. Mo yan diẹ kiun ninu pupọ ni, o jẹ ka pa yoku mọ dijọ miran. Ki Ọlọrun da awọn Ọba wa si, ki wọn jọba pẹ lori wa, ki igba wọn si tu awa lara, kẹmi tiwa na si gun.

ADELANI GBOGBOADE
*Akọwe Ẹgbẹ Owu ti Eko.*

Eko, Ijọ 15, August 1922.

## PREACHERS FOR TOMORROW.

### AWỌN ONIWASU ỌLA.

### WESLEYAN.

| Time—Tinubu | | Preacher. |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Rev. | A. N. Cole |
| 7. p.m. | ,, | E. K. A. Ajagbe |
| 10.30 a.m.—Ọlowogbowo | ,, | E. E. Williams |
| 7. p.m. | ,, | S. A. Pearce |
| 10 30 a.m.—Ereko | ,, | E. K. A Ajagbe |
| 7. p.m. | ,, | A. N. Cole |
| 10.30 a.m.—Ọbun-Eko | ,, | D. L. Mojọla |
| 7. p.m. | Mr. | E. E. Ajọṣẹ |

### AFRICAN COMMUNION.

| | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m.—Jehovah Shalom | Revd. | J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | ,, | M. B. Newton |
| 9 a.m.—Erelu | Mr. | J. H. Lawson |
| 4 p.m. | ,, | ,, |
| 9. a.m.—Bethel | Revd. | N. D. J. Ṣomuji |
| 6.30 a.m. | Revd. | E. A. Akinọla |
| 10.30 a.m. U. N. Methodist | Mr. | Samuel Johnson |
| 4 p.m. | ,, | H. A. Williams |

### BROTHERHOOD CHURCH

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m.—Ilupesi | Mr. S. A. Coleman Daniel |
| 7 p.m. | Pastor A. Adedeji Iṣọla |

## IPADE AWỌN ILU PẸLU AWỌN OLOYE ONI-FILA-FUN-FUN NI ILUPESI.

*August 18. 1922.*

Ninu ipade yi ọpọlọpọ awọn Imale li o wa, awọn Oloye mẹrin li o joko sori aga ti o wa nibẹ : Oloye Ọbanikoro, Oloye Eletu Odibo, Oloye Oluwa ati Oloye Suẹnu. Ipade yi bẹrẹ ni agogo marun gere, nigba ti ipade bẹrẹ Oloye Oluwa jiṣẹ ohun ti o ṣẹlẹ lọdọ Arọpo Igba-Keji Gomina, Ọgbẹni Roberts ni Saturday ọjọ karun oṣu (5th August.) Oloye Oluwa sọ pe Ijọba ni on ti fi ọrọ Eṣugbayi Eleko ti sibi kan, ati pẹ awọn ti pa a, awọn ti sin i, atipe awọn ko ka a si bi Olori Ile Dosumu mọ, ati pẹlu pe ki awọn Oloye lọ sọ fun awọn Ọmọ-Oba ki wọn lọ mu ẹlomiran wa lati rọpo Eleko, awọn koni ba a ṣe pọ mọ, ṣugbọn Oloye Oluwa sọ pe awọn ni " Bi Ọba kan ko ku, Ọba kan ko jẹ." Sibẹsibẹ Ọgbẹni Roberts-Igba Keji Gomina taku o ni Ijọba ko lesi si eyi, ki nwọn sa lọ mu ẹlomiran wa. Nigbati o ṣe, Oloye Ọbanikoro sọ fun awọn agba ilu ti o wa nibẹ pe ki wọn tẹ. Nigbati o ṣe diẹ si, nwọn pada de, Bọkinni kan sọ pe ohun ti nwọn ro ni pe ki nwọn ma lọ bẹ Ijọba titi, ati pe boya ni ọjọ kan awọn le ba oju rere wọn pade, o fi Ijọba we Olode (Small Pox) ti o jẹ pe bi o ba kọ lu enia, afi bi nwọn ba nlo ogun ẹrọ si i, bi bẹkọ ti nwọn ba ni ki nwọn lo ogun lile si i ko bale san were, nigbana ni o ma gbija, o ni nitorina ẹbẹ ni o yẹ ki a fi pade ọrọ ti Ijọba wi.

Nigbati o pẹ diẹ lẹhin eyi ni Yesufu ... o gbadura fun awọn Oloye ati fun aw... nigbati awọn tẹ, ẹnu wọn ko dọgba, o... eyeti ko ba ara wọn mu, o ni ohun ko... Ilu lọ si ibi kankan mọ afi bi awọn ... mura giri ti nwọn ba nlọ bẹ Ijọba pẹlu ... o ni lọna kini, awọn Ọmọ-Ọba joko nw... nwọn ni ki awọn Oloye nikan ma lọ lọ... ni lọna keji awọn Ọmọ-Ọba ko mọ pe... baba wọn ni Ijọba mba ja, o ni Ijọba ko b... Oloye ja, bikoṣe awọn Idile-Ọba, o ni lati... alaiye ti da aiye o jẹ aṣa awọn baba wọn lati Ọba jẹ, o ni ṣugbọn bi wọn ba jẹ ki aṣa ... yipada ni akoko tiwọn, o ni o di ọwọ wọn.

Nigbati o ṣe diẹ, nwọn ni ki awọn ọmọ Ile... ko fi esi si ọrọ yi, o pẹ titi ki ẹnikan to did... wọn, awọn Oloye si sọ fun wọn pe akoko ... ti kọja. Nigbana ni awọn Oloye sọ fun aw... pe awọn agba-gba yio dorikodo si ọrọ na, ... nwọn ba ro, nwọn a jẹ ki nwọn gbọ. ... ipade yi pari si.

Ẹnyin ara Ilu Eko, gẹgẹ bi ọrọ Ọgbẹni ... Agoro, o dabi ẹnipe ọrọ na ti ga ju bi a ti ... o ti koja eyiti a le fi ọwọ yẹpẹrẹ mu, o ma... gbogbo Ilu ki o tun dide lẹkan si bi ti idun... na ma ngbo si ni. O yẹ ki awọn Ọmọ-Ọ... awọn Idile-Ọba ati awọn ti o fẹran Ilu ... wọn dide si ọrọ yi girigiri, awọn Ijọba ... Eṣugbayi ti patapata niyẹn. Ẹ mura gir... ẹnu nyin ko sọkan, bi bẹkọ ọrọ na yio... ki Ọlọrun ma jẹ ko ri bẹ. *Amin.* Aip... mọ nipa Iwe-Ẹbẹ ti Ilu nkọ nwọn san... ribi-ribi ni Ilu ti na lori rẹ, bi Iwe-Ẹbẹ ... ko bani muro, o yẹ ki Ilu dide bi ọkunr... (*As one man,*) ki nwọn lọ bẹ Ijọba. Ẹn... nka iwe-irohin Ilu yio mọ pe ọrọ yi nfẹ ki... Ilu ṣigangan lọ si Ile Gomina ki nwọn lọ...

A ko ni ye ma sọ eyi, o wun ni pe ki... Alade papa mura si ọrọ ara rẹ ju eyiti... ma ṣefun lọ, ki on papa wa enia meji ta... ara rẹ ati awọn Oloye rẹ ki nwọn ko ọrọ... Ọgbẹni Carr Alabojuto Ilu (*The Resi... Colony,*) o wu ni ki Eleko ma lọ sọdọ r... gbo, ki o fi ọrọ ara rẹ ko ọ lẹrun. " Bi... ibi ti a fi nlọ, a mọ ibiti a ti mbọ."

Lẹhin na ki o ni ki o mu on lọ si ọd... Gomina, ki o tun wa aye ki o lọ fun ... Gomina papa ko si bẹ wọn.. Boya a ... ti o ma wipe eyi ti ṣe le wọ ? A ro ... le wọ. Ẹnikẹni ti o ba mbẹbẹ ni o ... Nitori ti Eleko fẹ ki ija tan, o yẹ ki o... ko awọn enia rẹ lẹhin ki o lọ si Ile Ọ... wọn. Eyi yio ran Iwe-Ẹbẹ lọwọ ... Awọn Ijọba a mọ pe ko mọ iwe iko, ṣu... o ba fi ẹnu ara rẹ sọ niwaju wọn' o... eyiti a kọ sinu iwe lọ. A tan ma p...o, ran Ilu ati Eleko lọwọ lati ri ohun ... lọdọ Ijọba. Ọrọ Eleko ti kọja eyiti yẹpẹrẹ mu.

" ELET...

## ERTISEMENT RATES.

IN EKO AKETE.

| | £ | s | d. | |
|---|---|---|---|---|
| and under ... | | 2 | 6 | weekly |
| ditional line ... | | 0 | 6 | do. |
| moriam ... ... | | 4 | 0 | do. |
| ... ... ... | | 4 | 0 | do. |
| ks for sympathy, etc., | | 5 | 0 | do. |
| rter page ... ... | | 5 | 0 | do. |
| a page ... ... | | 7 | 6 | do. |
| e page ... ... | | 15 | 0 | do. |

## OWO IPOLOWO ỌJA.

I IKEDE NKAN MIRAN NINU IWE-IROHIN EKO-AKETE.

| | | | |
|---|---|---|---|
| la mẹwa tabi didinku ninu rẹ. | 2 | 6 | ọsọsẹ. |
| titun kọkan | | 6 | do. |
| nti Ẹni ... ... | 4 | 0 | do. |
| ... ... ... | 4 | 0 | do. |
| ẹ ... ... ... | 5 | 0 | do. |
| ẹrin page kan ... | 5 | 0 | do. |
| do. do. ... | 7 | 6 | do. |
| ogbo do. do. | 15 | 0 | do. |

advertisement fees payable to the Editor direct.

bo owo wọnyin ṣọwọ si Editor tara.

## Advertisements.

IPOLOWO ỌJA.

—:o:—

GBOGBO ENIA DUDU,

ORUN AFRICA LABẸ GẸSI.

ade ti Ẹka Ẹgbẹ yi l' Eko ni ọsọsẹ Alaruba, (*Wednesday*,) Hall, Williams Street, ni agogo ni irọlẹ.

Gbogbo Enia lape sibẹ.

AWON ẸGBE OYINBO ONISOWO TI A NPE NI

E. H. STEIN ARA HAMBURG.

NEUERWALL 16 18. GERMANY.

Jẹ Awọn onişowo ti Ilẹ Enia Dudu, nwọn ma nranşẹ Ọja fun ẹnikẹni to ba fẹ'ibaşe Ọja ti Ilu Gẹsi tabi ti awon Ilu oyinbo miran ta o wa lagbegbe *England* ati Germany.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekurọ ti a ba fi ranşẹ siwọn si Ilu awọn oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Kosi ewu kankan ni fi fi Ọja-kọja ranşẹ si won lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn oyinbo yi şowo lọri tabi ki o kọwe si Aşoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No 3, tabi ni ibi-işẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street.*) ati ni ibi-ifi Ọja pamọ si (*Porto-novo Market Store*) L' Eko.

Ẹnikẹni le kowe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Oruko adugbo awọn oyinbo onişowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK. Hamburg.

## "OŞEWỌNI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aşẹ lọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

## Banuso ma b'enia so!

A nta Iwe Oyinmọmọ yi ni C. M S. Bookshop nibi, kọbọ mẹrin pere ni ọkọkan (4d.)

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

(*Macaulay's Household Dispensary.*)

A nta orişirişi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni popo-nla (*Broad Street,*) l' Eko ni owo pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun, Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Aşẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser.*) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DANWO: Ogun rẹ jẹ bi idan.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.